# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

NO 1,703 MONDAY FEBRUARY 21, 1966 (2D)


## Onikoyi Filę Şaşǫbora

EKO:— Ni ojo Eti ti ise ojo kejidinlogun osu yi ni irohin kan kakiri ilu Eko pe Oloye Ewrin Ayǫǫla Bajulaiye ti ise Onikoyi ti ilu Eko jalaisi ninu ile re ni Porta Street Eko ati pe irohin na fi ye wa pe ni ojo ojo Bo tiise ojo ketadinlogun osu yi ni Ologbe Oloye na ti ku ofan aisan die kan ti o se, eni odun mejilegota ni Ologbe Edwrin Ayǫǫla Bajulaiye ise.

Irohin fi ye wa pe Oloye Onikoyi ni eni keta ti yio je Oye Onikoyi ti ilu Eko ati pe ninu odun 1930 ni Oloye Edwrin Ayǫǫla Bajulaiye je oye Onikoyi ti ilu Eko.

Oloye Edwrin Ayǫǫla Bajulaiye ni oloye keta ti yio je oye Onikoyi ti ilu Eko ati pe on ni eni akoko ninu awon ijoye oni fila funfun ti yio je okan ninu omo ile Igbimo Ijoba ibile ilu Eko eyiti on pelu Ologbe Adeniji Adele koji Oba ilu Eko tele jijo wa ninu ile Igbimo Ijoba ibile ilu Eko gegebi Oloye eyiti awon npe ni Idejo.

Ologbe Onikoyi bi omo mefa sile eyiti iyaafin Ibironke Onikoyi ti o je Onisowo pataki ni ilu Eko je okan ninu awon omo ologbe na.

Bakanna ni Oloye Edwrin Ayǫola Onikoyi si fi opolopo iyawo sile lo pelu. Ni ojo Isegun ti ise ojo kejilelogun osu yi ni awon yio sinku Oloye na lehinti awon ba se efutu fun, eyiti yio gba ojo meta. Ni ojo Aje ti ise ojo kokanlelogun ni awon yio se ayeye inawo ni ile Ologbe Oloye na.

# AWỌN ỌLỌPA MU FANI ỌBA AKRAN WA S'EKO!

ĘKO. Qrọ di bi o nlọ ki o yago kuro loju ona fun mi nigbati gbogbo awọn enia gbọ wipe, awọn Qlopa-nu ti mu Oloye Rẹmi Fani-Kayọde, Ọba Cladius Akran ati awọn enia mẹwa miran pẹlu wọn wa si Eko ni opin ọsẹ ti o kọja lọ yi ni ọjọ abamẹta ti işe ọjọ kọkandinlogun oşu yi.



Oga'gun Aguiyi Ironsi

Olori Ijọba Ologun ilẹ Naijiria

Oniwe Irohin wa Ejongboro ti oro na se oju re se alaye fun wa ni ale ana wipe, nigba ti moto ti o ko awon enia na kuro ni Ibadan ti de Eko ti moto awon olopa na ti nwon npe ni "Black Maria" ti wo Eko, beeni gbo gbo awon enia ti mo wipe, awon enia ejoji kan wa ninu moto na.

Were ni gbogbo awon omode, agbalagba Okunrin ati Obinrin na beresi sare tele moto na lehin ti nwon si ba moto na sare de Ikoyi nibiti moto na ko gbogbo awon enia na lo.

Nigbati nwon de iwaju ogba ewon ni Ikoyi, ni moto na ba duro, ko si pe pupo lehin ti moto awon olopa na duro, ni gbogbo awon enia na ba beresi ma a sokale ninu moto

Irohin fi ye wa wipe, gbogbo awon ti nwon tete sare de iwaju ogba ewon Ikoyi ni nwon ri awon enia na ki nwon to ko awon wole lo, sugbon nigbati o ya ni awon olopa nu tun ko awon enia na lo si Tesan won

Nigbati nwon ko won de Tesan awon olopa-nu, gegebi alaye ti Oniwe Irohin wa Ejongboro se fun wa, nwon ko awon enia na wole lo lati dawon duro die, su gbon ko pe pupo lehin eleyi ni oga ninu awon Qga agba fun awon olopanu na Ogbeni M. A. Ibekwe de ti o si mu awon enia na wo inu yara miran lo

Nigbati o mu won wo inu yara lo tan, ni o wa beresi ma pe awon enia na ni okookan, ti osi nbi won lere, sugbon nigbogbo igbati o fi npere oro lowo awon enia na wonyi, ose ni awon olopa duro ti awon enia ti nwon ku nile, nigbati Ogbeni Ibekwe bere oro lowo awon enia na tan, ni awon olopa bi tun ko gbogbo won pada si ogba ewon Ikoyi

Sugbon nigbati Ogbeni Ibekwe bere gbogbo awon ohunti ofe bere lowo awon enia na tan, ni Ejongboro wa lọ si odo re, o si bere oro die lodo oga agba awon olopa na ninu awon ohunti o bere lowo awon enia na ati bi oro awon enia na ti bi oro awon enia na ti se je ki awon olopa-nu to tun lo ko gbogbo won wa si Eko lati Ibadan

Sugbon Ogbeni Ibekwe ko lati so awon ohunti o bere lowo awon enia na fun Ejongboro, sugbon o so fun Ejongboro wipe, "Bi o ba fe bere ohunkohun nipa awon enia wonyi ati ohunti nwon wa se ni Eko, lo si odo akowe Ikede Irohin fun awon olopa ni Eko, Qgbeni Bob Ezekiel Hart ni ile ise re ni Obalende, gbogbo re ni yio so fun o patapata"

Lẹsẹkẹsẹ ni Ejongboro gbe ẹrọ gbohungbohun ti o si fi pe Qgbẹni Hart ninu ile işẹ rẹ, Şugbọn Ọgbẹni Hart sọ wipe nitootọ ni awọn Ọlọpa lọ ko awọn ọmọ egbẹ Oşelu kan lati Ibadan wa si Eko lati bere awọn ọrọ kan lọwọ wọn, şugbọn o sọ wipe, on ko ti mọ oruko awọn enia na,

O si pari ọrọ rẹ bayi wipe:— "Ohunti mo le sọ fun on nisisiyi ni yi, Ọgbẹni Ejongboro, odabọ o



Oloye Fani - Kayode

Onirohin wa kan ran wa leti wipe ni ọjo Abamẹta ti işe ọjọ karun ọşu yi, ni awọn Ọlọpa lọ mu Oloye Rẹmi Fani Kayọde, eniti o ti fi igbakan jẹ Minista eto awọn ọgbin ati Igbakeji Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwo Orun Naijiria tẹlẹ ri ati Ọba Cladius Akran, ẹniti o ti fi igbakan jẹ Minista Alamajuto eto inawo fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria tẹlẹ ri ati awọn enia mẹwa miran,

Awọn enia ti awọn Sọja ti mu na nisisiyi ni: Oloye Rẹmi Fani Kayọde ẹniti o ti fi igbakan jẹ Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ati Min... Alamojuto eto awọn ohun Og...

Ọba C. D. Akran, ẹniti o ... kan je Minista Alamojuto eto ... tele ri Ogbeni Babatunji Olo... ku eniti o ti fi igbakan je ... Alamojuto eto Idajo ati ofin

...n o. ... ...koto tan, ...Post age 9d ...owo tirẹ ra...

...SAN KOGB... SERVI... 8 Idumagbo ... Lagos N... Leti oja Jan...

Wo oju ewe K...

# ARE IDARAYA ATI BI ATISE NKỌNI NI ARE SIṢE

PRAGUE:- Ogbẹni Kono Ichikawe, okan ninu awọn ọjọgbọn Onlwe Irohin fun ile iṣẹ Minista Alamojuto eto Irohin fun Ijọba orilẹ ede ilẹ Czechoslovakia ti fi han gbogbo aiye aworan are ti gbogbo awọn enia yika gbogbo awọn orilẹ ede aiye lọ ṣe ni Tokyo ninu ọdun 1964 bi awọn enia na ti ṣe ṣe daradara to ninu are ti nwọn ṣe ninu ilu na nigbana

Sugbon gegebi ise Ogbeni Ichikawe, ayafoto ni o nse, o si ti ya gbogbo awon enia na ni aworan, tabi nigbati awon enia na p de ninu ilu Tokyo ninu odun 1964, bi awon enia na ti se nso ara lotun ati losi ni Ogbeni Ichikawe nya gbogbo rẹ ni aworan.

Nigbati nwon si pari are na tan, ni o ba beresi maa fi awon aworan na han gbogbo awon enia nigbati o padade si ilu Prague ti ise Olu ilu fun Czechoslovakia bi awon enia na ti se se are ti nwon lo se ninu ilu na ni odun 1964.

Eleyi lo fun egbaagbeje awon enia ti nwon ko le lo si inu ilu na lati lo woran are na nigbana ni anfani lati ri gbogbo awon ohunti nwon se nibe ti nwon si fi ri gbogbo won ninu aworan

Sugbon nigbati y lo ya awon aworan na o ya awon miran ni oupa awon kan ni dudu ati awon yoku ni funfun ohunti o wa ya gbogbo awon enia lenu ni wipe aworan awon enia ti nwon se are ese nikan lo ya fun gb gbo enia nigbana lati ri gegebi o ti se je wipe ere ese lewu lopolop ti awon enia ko si feran are ese jija.

Ni tooto gbogbo awon enia ni nwon korira are ese jija ti nwon ko si tun feran are na eyi ki se ninu ilu kansoso sugbon o fere je wipe yika gbogbo aiye ni awon enia ko ti feran are ese jija yi.



## Ha Kini Eleyi

OGUN A PA YANMU—YANMU
OLORI ERIN MẸTA

Three Elephant Brand mosquito coils dara pupọ A n
O dara jul gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ'
O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia orun rẹ si dara pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ. Bakanna ni o si tun yara pa ayan ati ide ,
Teto lọ ra packet ogun yanmuyanmu, Three Elephant Brand coils tirẹ loni, ki o si danwo; iwọ y o ri bi o tiṣe ti gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọn ọmọ [illegible] yio si sun daradara
[illegible] o ri daju pe ogun yanmuyanmu, ori erin mẹta ni [illegible] fun ọ
[illegible] Three Elephant mosquito Brand coils yi wa ni ṣọbu [illegible] kakiri Orilẹ ede yi

Distributor

AMOS GRENLE & BROTHERS
34: Docemo Street Lagos.
6 & 11 Balogun Street West


Ni egbe keji ewe enia ko gbodo polongo are na ju bi o ti se ye lo nitoripe ni gbogbo ibiti nwon ba gbe nso oro n ni nwon ti maa nso pelu eriyanjiyan ti o gbona gidigidi ti enikan ko si fe fun en keji re ni aye lati so oro ti enu re fun awon enia gbo ki nwon le mo oro okan tire na nigba ti nwon ba nsoro,

O tun se alaye ninu oro re si wàju pelu wipe nigbayowu ti enia kan ba maa fi ara pa ninu are ese oluware gbodo ni ogbe ti yio mu inira opolopo wa fun oluware eyiti yio je wipe nwon gbodo gbe oluware lo si ile iwosan ni.

O tun ran gbogbo awọn enia leti wipe nigbati nwọn berẹsi maa wadi gbogbo awọn enia ti nwọn se ija— mba ninu are ẹsẹ jija laipẹ yi, Ijọba se ikede wipe, adọtalerugba awọn enia (250) ni nwọ fi are pa ni— gbati nwọn nja ẹsẹ ninu ọgba, ṣugbọn nigbatinwọn gbe awọn enia na de ile wọn, nwọn ku patapata, laiko ti ka awọn enia nwọn fi ara pa ninu ija are ẹsẹ ti nwọn si ri iwosan ịẹhin igbati nwọn gbe wọn ku— ro ninu agbo Iẹhinti nwọn se wọn lese tan nibiti nwọn gbe nja

Nigbati awọn Dokita tun nsọrọ laipẹ yi, nwọn ri wipe enia mẹrinlelọgọta 64 ni nwọn ti tun gba wa si ile Iwosan yika gbogbo aiye larin ọdun mẹrin sẹ— hin yi ti gbogbo awọn enia na si tun ku nigbati nwọn ṣe Iṣẹ fun wọn tan tabi ki awọn Dọkita to ṣe Iṣẹ fun wọn.

Nigbati nwọn tun ṣe ayẹwo gbogbo awọn enia wọn yi, nwọn ri wipe ninu awọn enia mẹrinlelogota na, enia mejiịelogun lo ku nibiti nwon gbe nja lọwo,

Ṣugbọn ninu ip de kan ti awọn Igbimọ are ẹsẹ ṣe ninu ilu Czechoslvakia lenulọlọyi, awọn alaṣẹ Igbimọ na sọ wipe, awọn gba gbogbo wọn enia ti nwọn ba fẹ ma ṣe are ẹsẹ tabi awọn enia ti nwọn ba fẹ maa fi are ẹsẹ ṣe iṣẹ lo ra fila agere onirin kan lati maa de nigbati nwọn ba fẹ lo ja are ẹsẹ.

Nigbati nwọn ba de fila onirin yi, bi awọn ẹnikeji wọn ba gba wọn ni ẹsẹ ni ori eleyi ko ni jẹki ere na dun wọn de ibiti yio gbe le pe wọn bi o ti ṣe maa npa ọpọlọpọ ninu awọn enia na

Irohin awọn Dọkita sọ wipe, nigbati awọn ti wọn nṣẹ are ẹsẹ ba nja, nwọn a ma lu arawọn ni ẹsẹ ni oti nigbati nwọn ba si ṣe eleyi. ọpọlọpọ wọn a ma daru lo ri wọn, gbogbo wọn ni wọn yio kuro ni aye ti nwọn ti wa tẹlẹ nwọn yio si bori ibomiran ti ko yẹ ki nwọn wa.

Nigbati nwọn ba ṣi ti ṣe eleyi, awọn enia na ko ni mo ohunti nwọn nṣe mọ, igbadun ko ni si fun wọn, bi nwọn o ba si tete gbe wọn lọ si ile Iwosan ki wọn to ṣe iṣẹ abẹ fun won, wọn le ku. Nwọn si tun le ku bi Iwosan ki nwọn ko ba tete gbe iru awọn enia bẹ lọ si ile Iwosan,

Ohunti o si mu awọn enia ro ọrọ yi ni ti iku odo mọdekuurin kan, Stanislay Patocka, ẹniti o ku lojiji ni goati on pẹlu ẹnikan nja ẹsẹ ni ọjo kan, nigbati awọn Dokita wo ohunti o pa Ogbẹni Patocka. eni ọdun mẹdogoon. nwon ri wipe ẹnikeji rẹ lun lẹsẹ lori ni, opolo ori rẹ si ti ku-

Wo Oju Ewe Kar n

OLOTU IRANWO ... Iwe si Olotu Irohin Imole

## A Nfę Ojo Oja Ninu Irohin Imolę

Olotu, mo ro pe o ti to odun kan abo bayi ti a ti ri ojo oja ilę Yoruba ka ninu iwe Irohin Imolę eyiti o ję wipe lęsęsę ni a ma nmọ asiko awọn ọjọ oja ninu Iwe na, şugbọn a ko mọ ohunti o da Olotu pęlu awọn Alabaşişępọ rę ti nwọn ko fi şe eto nipa awọn ọjọ oja Ilę wa eyiti o ję wipe o je ohunti o şe pataki pupọ awa onkawe nyin si ma ngbadun pupọ lati ma ri i ka

Mo ro pe Olotu Irohin Imolę ba le tete jęki a ri awọn ọjọ oja wa kaninu iwe Irohin Imolę bayi Eleyi si tun ję ohunti o şe pataki fun awa ti a ję Onişowo nipa itọka sọna ti iwe Irohin Imolę ma a nşe fun wa nipa ọjọ oja.

Inu awa Onişowo yio dun bi Olotu ba le şe eto gęgębi a o ti şe ma ri ọjọ oja na ka ninu iwe nyin laipę yi. A o si ma reti nyin ri omi pọn. Ę ku işę Olotu.

Emi ni
JIMOH BAKARE
IGBOGILA



Emi ni
James Aderibigbe.

## Oba Ileshin Nko?

Ọlotu Inu mi yio dun bi ę ba le ba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin to kun fun ọgbọn ati Afọbajẹ ilu Ileshaa, awọn Igbimọ ti Ijọba ibilę ilu Ilesha ati Ijọba Ipinlę Iwọ Orun Naijiria lati tete şe eto lori Ọba ilu Ilesha eyiti o tọ ti o si yę ki awọn enia ilu na yan Ọba titun fun ni ilę Ilesha mo ro pe eyiti Ọba ilu Ilesha ti waja bayi ti to ọdun męrin şęhin şugbọn lati igbana awọn ọmọ ilu na ko mọ asiko ti a o si tun ni Ọba titun miran.

Ọpọlọpọ awọn ọba lo ję wipe ti w,aja ni Ipinlę Iwọ Orun Naijiria ti nwọn si yan Ọba miran şugbọn o yę ki awa ọmọ ilę Ijęsha lọ ronu wa jinlę ki a si mọ ohunti a o şe ti a o fi yan ọba titun kia ma şe fi ọrọ işelu bọ eto ilę Ijęsha

Olotu mo dupę fun aye si gba mi' Ọkọ Ọba ko ni şa nyin ęsę o,

Emi ni
Akanbi Ajayi
ILESHA

## A dupę lowo Ijoba

Inu mi dun pupọ nigbati mo ka ninu Iwe Irohin Imọlę pe Ijọba ti toju owo goboi lati fi şe omi ęro si ilu Mushin o ti to ojo męjo kan ti a ti nkes Ijoba Ipinlę Iwo Orun paapa Ijoba ibilę Mushin lori omi ti a ki ri mu ni ilu Mushin.

Bi ko ba ję pe ọgbọn ti Ijọba Ipinlę Iwọ Orun nda nitoripe bi ibo didi ba nbọ ni awọn Ijọba ma nfi ęnu ya ęran sọbę, ko fi oju si asiko ti nwọn yio ba bere işę na bi ko ba jęọrọ ęnu lasan inu wa yio dun pupọ.

Mushin ję ilu nla larin ilę Naijiria o si tun wa ni arin olu ilu Naijiria ati Ipinlę Iwọ Orun Naijiria ki enia to wo ilu Eko ę ni lati de Mushin to ję nkan ti o buru ju lati ri pe omi ti wọn ju ni Mushin, ki a to ri omi mu wahala nla ni a nş. a ko sọ pe ao le ra garawa omi kan ni kọbọ nigbati awa kori omi ra nkọ Elomiran larin wakati męjọ kon.

## Kini O Mu E Ronu Nipa Awọn Asọ Rę ?

Bi o ba ni asọ fun fifo tabi lilo ni asọ bi owu (woolen) tapeta, asọ oke, Guluca Brocade ni ti Ọkunrin tabi ti Obinrin. A ni orişirişi asọ ti o ba ni fun fifo tabi ti o ba fę yi awo ara asọ na si miran (Changing of Colours]

*Tete Gba Wa Si Ọdo*

**Iwajowa Cleaner Enterprises**

87. Ọdunfa Street,
Phone 40029 Lagos

Kia ni ao bi ọ fọ, ti iwọ yio si ri gba ni şękanna, O le rannşę si wa ki a wa ko awọn asọ rę na tabi ki o pe wa ori ęrọ isọrọ (telifonu) ti nọmba rę wa loke iae yi.

Bakanna ni a si tun nba enia gbọn ilę rę nu tabi bi o si fę kun ile tabi ile işę rę, işę wa tun ni yọn na Bi enia ba si fę kọ ile tabi o şęşę kọ tan o si fę kun o le gbe fun wa ki a ba kun, ki a si ba şe lọsọ ti yio ję oju ni gbese, A ni gbogbo işę ti o ba ti ję ki a tun nkan şe ni o nşe işę tiwa.

Dan wa wo lękanşoşo ki o sa ri bi işę wa ti dara to.
Owo pọku ni a si ngba.

# Ę maa Ka Iwe Irohin Imolę Lojojumo

# KERE O! KERE O!!

## Awọn Tani Wọnyi ?



LATI OWO OSI:- ỌNI ADELEKAN (Olubuse) ENIKEJI:- ỌNI ADEMILUYI (Ajagun) ENIKETA:- ỌNI ADEREMI (Afọbatęle)

AWỌN ỌMỌ DUDU WA MẸTA TO JOYE "ỌNI" TẸLE ARA WỌN

ITAN WỌN DUN KA

Nję o ti ra ninu itan Igbesi aiye Oduduwa ati ti awọn ọmọ rę" to şęşę jade?

Bi o ko ba ti ra a, mase jafara, nitoripe, bi awo ran awọn "ỌNI" męta yi ti şe je ohun iyanu la ti le ri wọn papọ, Ęeni itan wọn rę ninu Iwe na.

Mase ę ki nwọn ro hin rę fun ọ, Tete lo ra tire koto tan, 3/- pere ni, Postage 9d
F'owo tirę ranşe si.—

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8 Idumagbo Avenue
Lagos Nigeria.
Leti oja Jankara)

# Okunrini kan ati iyawo rẹ wẹwọn ọdun mẹfa

AKURẸ, Ninu ile ejo Ganran ti Akure ti Adajo agba ile ejo na ti pase pe ki okunrin agbe kan Mathias Okei ati iyawo re Virginia ti nwon ngbe ni ilu Ondo yara lo fi ewon odun mefa jura lori esun ole jija, ile fifo ati pe awon odaran t'oko t'aya na gba eru ole sile ninu esun ti ile ejo Ganrun na fi kan awon enia na ni pe nwon tun ba ile onile je eyiti oko yio lo odun marun l'ogba ewon ti iyawo yio lo odun kan bakanna.

Ninu oro olopa to ba awon odaran na sejo ni o ti se alaye fun ile ejo Ganran na pe ni ojo kejidinlogbon osu kesan odun to koja lo yi ni Okei ji ponun mewa (£10) lowo Tunde Peters ise akeko ninu ile eko giga kan ni Ado Ekiti. Olopa na tun se alaye ninu esun ti o fi kan odaran na ni pe o tun ya aso omokunrin na nigbati odaran na fe fi agbara gba owo na lowo omo ile eko na

Olopa to ba awon odaran na sejo tun se alaye pe nigbati odaran okunrin na gba ponun mewa (£10) na lowo omo ile eko na ni o ba ma fun iyawo re ti iyawo odaran na si salo.

Ninu idajo Adajo agba ile ejo na ogbeni Joseph Beckley ni o ti se alaye pe gbogbo oro ti olopa to ba awon odaran na sejo ni o te on lorun ati pe otito ni awon enia na se ise na.

Adajo na si pase pe ki oko lo fi ewon odun marun jura eyiti iyawo odaran na si fi ewon odun kan jura pelu.

Ninu ile ejo kanna si Adajo agba ogbeni Joseph Beckley ti tun pase pe ki okunrin agbe kan Julius Akinkogbe lo fi ponun meta dogbon tanran tabi pe ki o yara lo fi ewon osu meta jura lafaraba lori esun pe odaran agbe na ni awon ogun kan eyiti o lodi si ofin Ijoba lowo.

Ninu oro olopa to ba odaran agbe na sejo ni o ti se alaye pe odaran na si ni abere eyiti nwon ngun fun enia ninu ile iwosan meta lowo ati awon iwe kan ti o je ti awon Dokita eyiti olopa na tun se alaye pe nse ni odaran agbe na ji awon nkan na ko nito ripe ko ri ra laije pe dokita ni ise

Olopa tun se alaye pe awon ohunti nwon ka mo okunrin odaran na lowo je ohunti o lodi si ofin lati ri lowo enia ti ki ise Dokita to nse itoju awon alaisan

## YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan 22 Feb 20) Mase jẹki ara rẹ gbo na lori ohunkohun ju mase jẹki gbọmọgbọmọ tirẹ pọju, ṣugbọn ko buru bi o ba ṣa ni iwọ ntunwosi.

PISCES (Feb 21 Mar 20) Mase nikan joko sile ki anrẹ tabi ki otutu ma mu ọ, ṣugbọn ki o jade tọ awọn ọrẹ rẹ lọ ki ẹ si jumo ma mu faaji ki ẹ si ma daraya.

ARIES (Mar 21 April 20) Ire mbẹ fun ọ loni. o si yẹ ki o di ara rẹ ni amure fun orire ọjọ oni, igbadun ati idunnu ni yio je fun awon iyawo rẹ.

TAURUS (April 21 May 20) Ọna bi ọran ara rẹ ti ngba lọ yi ko y o s, nitorina, mase ponara rẹ ju ṣugbọn ki o gba eyiti Olorun ba mu wa Ayọ mbọ lẹhin rẹ.

GEMINI (May 21 June 20) Ṣe eto gbogbo ohunti iwọ yio ṣe oni ki o si fi ara mọ eto na yio si yọri si rere.

CANCER (June 22 July 20) Ọjọ itunu ni oni je iwọ yio si ma se re lọ geregere mase jafara ki o se leto bi gbogbo nkan yio ti lọ.

LEO July 23 Aug 22 Bi o ba ngbero kan lati ba enia kan se adehun papọ ot tọ inu ati ododo ni ki o sọ nibẹ itori pe adehun ti eo se ki ise nkan ti enia le da le rẹ

VIRGO Aug 23 Sept 23 Orlẹ rịgị ọrọ ti o w fu ọ lọna kini odabi pe are fẹ mu ọ ọna keji okan rẹ nfẹ ki ẹ jọ ṣidehon nitoripe ọ ... rẹ nda si meji

LIBRA Sept 24 Oct 23 Bi o ba le ma ba iṣẹ rẹ lọ iwọ yio fi ọpẹ fun Oluwa ti o fun ọ ni ọgbọn

SCORPIO Oct 24 Nov 22 Ire nbẹ pẹlu rẹ iọna gbo gbo oro ti o ba ba gbogbo eara sọ yio gba si ọ lẹnu

SAGITTARIUS Nov 23 Dec 21 Pirikiti ni ara rẹ lọ ni ṣugbọn mase jẹki aseju ba ọla rẹ jẹ ire ni oro rẹ yio jẹ

CAPRICORN Dec 22 Jan 21 Ire mbẹ fun o loni na gbogbo awon ọnti o fẹ yio ma nifẹ rẹ siwaju lati nje oban ti o rọrun


GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ATI OGO

NIPA **DYNAMIREN** TỌNIKI

ALE-IBI-ALE Egbogi Tọki amọnu, titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ oju fun Agbara ati Ajẹbidan ṣẹ lara agbalagba Ọkunrin ati Obinrin gbogbo



Bi arẹ ara ba nmu ọ, ni gbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣiṣe ti o ko le jẹun dara dara, tabi ki o male sun dada de ọkan lọsan tabi awọn ṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Emi Breath inu ko ba kunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala sise tabi inu awọn aisera gbogbo nyin ti ọjọ ori (age) ba ti kọja ogbọn ọdun si adọrin tabi jubẹ lọ mọ daju pe DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara rẹ di ọtun pata oju rẹ yio si walẹ re kete alafia ati igbadun de Bere Dynamiren yi ni Ṣọbu awọn :-

Waterloo Medicine Stores
8 PalmChurch Street Lagos
22878 Lagos Nigeria (Ola Ita Faaji)
UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street Lagos

NIGERIAN MEDICINE STORES
Tinubu Square Lagos
LAGOS ISLAND CHEMIST
Nnamdi Azikiwe Street, Lagos
UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street, Lagos.

ATI NI ṢOBU
IṢE OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA
IBADAN



# Iwe Itaja 1966

Idamu owo ha wa fun ọ bi
Abiku ha nyọ ọ lẹnu bi
Airi iṣẹ se ha wa fun ọ bi
Ailera mba ọ ja bi
?

Iwọ le bọ ninu gbogbo wahala aiye wọnyi ti iwọ ba ra ninu awọn ohun Ijinlẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ti a to lẹsẹsẹ si isalẹ yi.

1 Iwe Egbogi Ajẹbidan 25/— di 22/6
2 Iwe Afọṣẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan 4/6 di 3/6
3 Iwe Itumọ Ala ati Ogun Wibẹjẹbẹ 4/6 di 3/6
4 Iwe Egbogi Awogba Arun 20/— di 17/6
5 Iwe Ilana Ifa Yanrin tirẹ ati etutu ṣiṣe 20/- di 17/6
6 Gbedegbẹyọ Hausa 3/—
7 Iwe Aniyan Iron 2/— di 1/—
8 Turari Iṣegun Ajẹ ati Itaja 10/6 Pangolo 2/6 paketi

Fi Owo ranṣẹ si
J. O. SHOYINKA
P. O. Box 159
MUSHIN
tabi
9, Iyala Street Oduabọrẹ, Mushin

# Are Idaraya Ati Bi Atiṣe Nkoni Ni Are

## Lati Oju Ewe Keji

ro ni aye ti o ti wa tẹlẹ ri.

Lojiji, ati lairo tẹlẹ ni Ogb, ni Patocka ba ṣubu lulẹ ti o si ku ni ojo na ti gbogbo awon ero ti nwon nworan si bẹlugbo ti gbogbo won tuka yanga mọo lori nibiti awọn gbe nja.

Ọkan ninu awọn ejo— goon orilẹ ede Ile Czecho slovakia Dọkita Henner ẹniti ise Ọga agba Ile Iwo san nibiti nwọn gbe nkọ wọn ni ise Dokita ni Charles Universsity, ni ilu Prague sọ ninu ọrọ kan wipe on ko are ese jiji larin awọn ọmọ enia nitoripe ki ise are ti o dara fun ọmọ enia lati maa ja.

Dokita Henner, sọ siwaju ninu ọrọ rẹ wipe, ọna ti nwọn ngba ja are ẹsẹ nisisiyi jẹ ọna ti ko dara rara t o si tun mu ewu lọwọ fun ọmọ enia lati maa ja

O wa daa ni imoran wipe, ki ba dara bi Ijọba ba le se ni ofin wipe, ẹnikẹni ko gbọdọ lu ẹnikeji rẹ ni ẹsẹ ni ori nigbati nwọn ba nja nitori ohunti awọn Dokita nri nipa ijamba wọnyi

O tun sọ wipẹ, gbogbo awọn ọdọmọde ti nwọn yio ba maa ja ija are ẹsẹ ki awọn Dokita maa ye wọn wo daradara ki nwon si ma gba wọn laye lati ma ja

Nigbati nwọn ba yẹ won wo ni ọdun yi, nigbati o ba tun di ọdun ti mbọ, ki awọn Dọkita tun maa ye wọn wo pẹlu, ki nwọn si maa se eleyi ni odo dun fun awọn ọmọde ti nwọn ba fẹ maa ja are ese

Ni ipari Dọkita Henner sọ wipe, awọn ohunti awọn Dokita na yio maa ye wo lara awọn ọdọmọde na ni ori wọn, ki nwọn maa ya aworan rẹ wọn ki nwọn si mo iro aye ti ori awọn ọmọ ng wa ki nwọn to ma gba wọn laye lati lo ja ija ti nwọn fẹ ja.

Nitoripe, ori awọn ọmọ miran ko tun dara wipe, ki enia gba wọn ni ẹsẹ ni ori, bi awọn ọmọ bayi ba si lọ ja ija are ẹsẹ, were ni rin awọn ọmọ ba yio ku nigba ti awọn ba gba wọn ẹsẹ lori ni ojo kan

---

# KERE O

Njẹ o ti ni ninu "IWE ITAN ODUDUWA osẹ sẹjade ?

Ha ! Kosemani ni iwe na jẹ fun ọmọ Yoruba Iwe na kun fun itan Isẹdalẹ Yoruba, Kedere ni aworan Oduduwa ati ti ọmọ rẹ han ninu rẹ.

Maṣe jẹki nwọn rohin Itan Ilu rẹ fun ọ
3/- pere ni. Postage 9d

Tete f'owo tirẹ ranṣẹ si:-

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8 Idumagbo Avenue Lagos Nigeria

---

# Ẹ maa Ka Iwe Irohin Imọlẹ

---

BEREFUN OJULOWO EGBOGI_

## "Congreve's Iodo Form—Ointment"



Atamataṣe ni egbogi" ADIBLEGBO" yi jẹ fun itọju gbo gbo orisirisi "EGBO—ESẸ" ni kiakia bi o ti wu ki jọ rẹ ti le pẹ to. Adielegbo yi ko ni egbẹ nipa wipe awn ko idọti ni bi ẹri gbogbo ti ba wa loja egbo patapata jade oju re yio si mo daradara .Lẹhinna oju egbo yi o ba jin sinu yio jeki oju re hu wa soke, yio si pọn daradara tun bakanna ko si mọ aerewere ni yio si san patapata Alafia de si ọ niyen ! –

Ri daju gbangba wipe awon sobu ti a da oruko won abssale iwe yi ni ogbe ranṣe lọ ra. Bibeko awon Elero ihii on ijibiti yio ta 'Adamodi' re fun o maṣe gba rara

Waterloo Medecine Stores
8. Palm Church Street P. O Box 333 Lagos

---

## IWE KOṢEMANI NI EYI

IWE ITỌSẸ OHUN GBOGBO NINU ODU MẸRINDINLOGUN

Iwe yi kun fun Asọtẹlẹ ati wipe, yio din ọ lowo YẸMIWO" ku, nitoripe iwọ na yio le ma da ṣe AYẸWO fun ara rẹ
KOSEMANI" ni iwe na, 2/6d pere ni a ntaj.
Postage 9d

ẸSAN KOGBOGUN SERVICES
8, Idumagbo Avenue
Lagos Nigeria (Lati Oja Jankara)

---

## The NEW HOOVER

Washing Machine
Makes Clothes
Whiter and Brighter
It's easier the....
**HOOVER** way

... clothes in 8 minutes all in one continuous operation. That's the ... performance of the new Hoovermatic a ... Washing Machine and Spin Dryer.



AVAILABLE AT
LEVENTIS TECHNICAL
MARINA – IDDO – IBADAN–
KADUNA – JOS – KANO–
P. HARCOURT – ABA
and Kingsway Stores.

